# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORE AIYE TẸNI GBOGBO LAWA

NO 1,589 SATURDAY DECEMBER 18, 1965 (2D)

## Ojẹwumi Tun J'are Ẹjọ

IBADAN; Ni ọjọ ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu yi ni Adajọ agba ile ẹjọ kekere ti ilu Ibadan paṣẹ pe ki Olotu iwe irohin "Naijiria Tribune" Ọgbẹni Ayọ Ojewumi ati okan ninu awọn ti o jẹ Olotu iwe irohin na Ọgbẹni Kan je Ẹlẹkọ ma lọ ni ayọ ati alafia, nitoripe nwọn ko ni ẹjọ kankan lati ro tabi lati jẹ niwaju ile ẹjọ na.

Ninu ẹsun ti nwọn fi kan awọn Olotu iwe irohin na ni Ọlọpa to ba wọn ṣe ẹjọ ti ṣe alaye fun ile ẹjọ tẹlẹ pe awọn Olotu iwe irohin na tẹ irohin kan jade ninu iwe irohin "Nigerian Tribune" eyiti o lodi si ofin Ijọba

Nigbati ile ẹjọ na fẹ ma gbọ ẹjọ na ni Abanirojọ ti Ijọba dide duro ti o si ṣe alaye fun Adajọ agba ile ẹjọ na pe on ko ni ẹjọ kankan lati ba awọn Olotu iwe irohin na ṣe ati pe on si ti fi ẹjọ na silẹ.

Ninu Idajọ Adajọ ile ẹjọ na ni o ti ṣe alaye pe nigbati Abanirojọ ti Ijọba ti kuna lati ma ba ẹjọ na lọ ni Adajọ na ba maṣe pe ki awọn Olotu na ma lọ layọ ati alafia.

## Adegbenro Sọ Pe :

# IBO-ATUNDI NI O LE PARI RUDURUDU IWỌ ORUN

IBADAN:- Ninu irohin kan to de ọwọ wa lori eto ti awọn Igbimọ kan ti a npe ni "Yoruba Elders Peace Committee" awọn ti nwọn fẹ pari edeaiyede to wa larin ẹgbẹ Itẹsiwaju (UPGA) ati Dẹmọ (NNDP) ni irohin na fi ye wa pe o ṣe iṣe ki ẹgbẹ Itẹsiwaju (UPGA) eyiti Adele Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre Alhaji D. S. Adegbenro nse Olori rẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun ma ṣe gba ki nwọn pari ọrọ na.

Oniwe irohin wa ni Ibadan fi ye wa ninu irohin rẹ pe awọn Igbimọ ọmọ ile Yoruba eyiti nwọn jẹ meje ti Adajọ agba fun apapọ Naijiria Oloye Adetokunbọ Ademọla iṣe Olori wọn ba Alhaji D. S. Adegbenro ṣe eto ipade kan lori bi nwọn yio ti ṣe pari ija na eyiti awọn Igbimọ na fi odidi wakati meji ṣe ni ile Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ni Oke-Ado Ibadan ni ọsẹ yi ni awọn Igbimọ na jiroro lati pari ija lori eto abayọri idibo si ile Igbimọ Asofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun eyiti nwọn ṣe idibo rẹ ni ọjọ kọkanla oṣu kẹwa ọdun yi.

Nibi ipade ti awọn Igbimọ awọn ọmọ Yoruba to fe pari ija na ni awọn die ninu awọn Igbimọ ẹgbẹ UPGA ṣe pẹlu Olori ẹgbẹ UPGA ni Ipinlẹ na Alhaji D. S Adegbenro.

Ninu ọrọ ti Alhaji D S Adegbenro ba awọn Igbimọ na sọ ni ọrọ ti o ti ntẹ ẹnu mọ tẹlẹ fun awọn Igbimọ na pe ohunti o le mu ki rogbodiyan to nṣẹlẹ lori eto iṣelu ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria wipe ki nwọn tete tu ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ka ki nwọn ṣe eto lati dibo miran eyiti



**Alhaji Dauda Soroye Adegbenro**

ADELE OLORI ẸGBẸ AFẸNIFẸRE

yio mu ki awọn enia Ip'nlẹ na le yan Ijọba ti yio ṣe eto akoso won lọna eto ofin laisi magomago

Irohin fi ye wa labele pe awọn Igbimọ ti nwọn nṣe eto lati pari ija na ba Adele olori ẹgbẹ Afenifẹre Alhaji D-uda Soroye Adegbenro jiroro lori bi yio tiṣe jẹki nwọn pari ija to wa larin ẹgbẹ (UPGA) ati Dẹmọ eyiti yio mu ki eto alafia ati isọkan le wa ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria

Ṣugbọn Alhaji D S Adegbenro si ni iteriba ati Ọwọ fun awon Igbimọ ti nwọn ba jiroro lori bi nwọn yio ti se pari edeaiyede to wa larin awon ẹgbẹ mejeji na ati pe o tun ṣe alaye fun Igbimọ na pe on ko fẹ yi ọrọ ti awọn ẹgbẹ on eyiti iṣe UPGA si sọ pe ohunti o le fi opin si rogbodiyan to nṣẹlẹ ni Ipinlẹ na ni re ki nwọn tu ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Ipinlẹ na ka ki nwọn si ṣe eto idibo titun miran ni Ipinlẹ na

Awon Igbimọ ẹgbẹ na ni Oba Adesoji Aderemi Oni ti Ile Ifẹ, Oloye Adetokunbo Ademola, Oloye Kofo Abayomi, Alhaji A. M. Elias, Bishobu ti ilu Ibadan Eni Ọwọ S O Odutola, Imam agba fun ilu Ibadan Imam Muili ati Oloye Aminu Koṣokọ.

Bakanna ni irohin tun fi ye wa pe awọn Igbimo na tun ba Oloye Samuel Ladoke Akintola ati awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmo (NNDP) jiroro lori bi nwọn yio ti ṣe pari edea yede to wa larin ẹgbe UPGA ati Demo lati le jeki rogbodiyan to nṣele ni Ipinle Iwọ Orun Naijiria le lọ si opin.

Bakanna ni awọn Igbimọ ẹgbe obinrin ti ile Yoruba ti nsowọpọ lati le jẹki edeaiyede to wa larin awọn ẹgbẹ UPGA ati Dẹmọ le pari lati le jẹki rogbodiyan to nṣẹlẹ ni Ipinlẹ na le lọ si opin ni Ipinlẹ na.

Awọn Igbimọ ẹgbẹ awọn Obinrin ti nwọn npe ni "Nigerian Council for Women Society" eyiti iya afin Abayomi jẹ Asiwaju wọn tun ba Alhaji Olori

WO OJU EWE KẸFA



Oba Adesoji Aderemi Oni ilu Ife



Ademola Adetokunbo Olori Adajọ Ile Naijiria

# Ẹ KU IPALẸMỌ ỌDUN KERESIMESI

## YẸYẸNATU

### Oniyẹyẹ Eko

Olotu: Yẹyẹnatu, Firifiri ni oju tile tun nri inu

Yẹyẹnatu: Bẹẹni

Olotu: Ṣe ko si nkan ṣa ?

Yẹyẹnatu: Họwu, bi ẹ ko tile gbọ ṣebi ẹ nkawe Irohin

Olotu: Ewo ni ẹ tun gbọ o ?

Yẹyẹnatu: Iyẹn nipe gbagbo oku ti o nsun ni West yẹn ko to ki nlọ fi eri ara mi pamọ?

Olotu: Ṣebi o ni o ki iṣe ojọ ?

Yẹyẹnatu: Bẹẹni, ṣugbọn igba ti mo tun ngbọ pe ọlọpa osọnu ni aiya mi ba oja.

Olotu: Ṣebi iwọ ki iṣe Ọlọpa

Yẹyẹnatu: Hahn, ọlọpa nikan ni o nsọnu ni ?

Olotu: Emi ko mọ kẹ Ewo ni temi ?

Yẹyẹnatu: Ha ! ẹru o ba yin ni ?

Olotu: Ẹru ṣe le ba mi.

Yẹyẹnatu: Oloye Akintola ni on ti ṣẹ epe pe awọn ọmọ ẹgbẹ UPGA ko ni ba awọn pe tẹlẹ ki ito to de

Olotu: Họwu, Yẹyẹnatu nibo lo ti gbọ iyẹn ?

Yẹyẹnatu: O wa ninu Daily Times kẹ ṣebi ni Ibadan ni o ti sọ bẹ ẹ ti o ni awọn agba sọ pe ko ṣẹ ko ṣẹ ni ti ila kọ ṣẹ nigbati on sọ bẹ ẹ

Olotu:- Iyẹn ni pe o lẹ sọ pe epe rẹ ni o ja ?

Yẹyẹnatu: ọjọ ti ẹ ba di lọya ni ngo da yin lohun

Olotu: Iyẹn ti fo

Yẹyẹnatu: Nitori kini ? Aiye atijọ ni o ti ṣoro lati di lọya kẹ

Olotu: Iyẹn ni pe ko ṣoro nisisiyi ?

Yẹyẹnatu: Ṣe ni aiye atijọ bi o ko de ilu Oyinbo o ko le di lọya, bi o lọ si ilu Oyinbo nisisiyi paapa o gbọdọ tun kọ lọya tiwa ni

Olotu: Yẹyẹnatu, Iwo na ma ti di oga nisisiyi

Yẹyẹnatu: Aidi oga ti jẹ emi na fẹ di lọya kẹ

Olotu: Iwo kọ Nitori kini ?

Yẹyẹnatu: Nitori iru tiyin bayi ni

Olotu: Lo si ilu Oyinbo

Yẹyẹnatu: Ha ha, ofin ti ilu Oyinbo yato si ti wa Bi loya Oyinbo de ibi bi o ti wu ki o gbona to, ko le mo bi a ṣe nṣe ẹjo tiwa nihin

Olotu: Looto ni yẹn ṣa

Yẹyẹnatu: Ko siro nibẹ ni toripe ida ilu ni iṣelu.

Olotu: Njẹ iwo na ko ni lo si University bayi ? o ma ti omo nkan nisisiyi gan?

Yẹyẹnatu: Ẹ ko ri mi lati ojo yi kekere ni ẹ pe ile ni?

Olotu: Iyẹn ni pe o nkawe lootoni

WO OJU EWE KARUN

---


## ALEBIOSU BOOKSHOP

13 BAMGBOSE STREET, PHONE (21304) LAGOS

LADIES & GENTLEMEN/

As your problem is ours, therefore we have got in stock, Seasonal Lovely & Interesting Xmas Cheque and Xmas Cards in assorted types as:-

| | |
|---|---|
| 1 To my Darling | 2 To my Sweet Heart |
| 3 ,, my Lover | 4 ,, One I Love most |
| 5 ,, my Boy Friend | 6 ,, Husband |
| 7 ,, my Wife | 8 ,, my Sister |
| 9 ,, Brother | 10 ,, my Friend |

You will be mostly impressed if you come to the above named Bookshop for your Seasonal Greeting Cheques & Xmas Cards.

WISHING YOU HAPPY CHRISTMAS IN ADVANCE


---

Mo ki gbogbo ẹnyin onkawe Irohin Imọlẹ pe ẹ ku ipalẹmọ ọdun Keresimesi Oduma e Ọba Ọlọla maṣe jẹki ọdun yi di wa mọ ẹru. Baba dakun jẹki oṣe ẹni gbogbo wa Amiin

Ni iwoyi amọdun ẹni ko ti romọ bi yio tọwọ bọ oṣu fi pa ọmọ lara Ẹniti o ba wa ni idubulẹ aisan yio san Aṣẹ.

Oluwa yio fi owo ṣe ọrọ gbogbo wa. Alafia Oluwa yio si ma a ba gbogbo wa gbe Amin ati Amin.

Mo mọ daju pe ọpọlọpọ ninu ẹnyin onkawe wa ni yio mọ iya si pe emi ko ni Shoyinka nki ku ipalẹmọ ọdun toripe awọn jẹ Imale, ṣugbọn mo fẹ ki ẹ mọ daju pe, yala ẹ jẹ onigbagbọ, tabi imale, gbogbo wa ni a jijọ ngmura de ajọyọ ọdun "Keresimesi na toripe ọjọ ibi Anabi Yisi ni i se,

Ki ngto pari oro mi, nko le ṣai sọ itan die fun nyin nipa ọjọ ibi Jesu Kristi ti awọn imale npe ni Anabi. Yisa,

Bi ibi Jesu Kirist ti ri ni yi:- Ni akoko ti a fẹ Maria Wundia fun Josefu ki wọn to pade a ri o loyun lati ọwọ Ẹmi Mimọ wa"

"Josẹfu ọkọ rẹ ti ṣe Olotitọ eniyan ko fẹ dojuti ni gbangba ṣugbọn o fẹ kọ silẹ ni ikọkọ.,

"Ṣugbọn bi o ti nro nkan wọnyi Angẹli Oluwa yọ si ni oju ala, o wipe Josefu ọmọ Dafidi, Maṣe bẹru lati mu Maria aya rẹ si ọdọ nitori eyiti o yun ninu rẹ ni lati ọwọ Ẹmi Mimọ wa ni"

"Yio si bi ọmọkunrin kan Jesu ni iwọ yio pe oruko rẹ Nitori on ni yio gba awọn enia rẹ la kuro ninu ẹṣẹ won',

"Gbogbo eyi si ṣẹ ki eyi ti a sọ lati ọdọ Oluwa a li ẹnu woli ki o le ṣẹ pe, Kiyesi Wundia kan yoo loyun yio si bi ọmọkunrin kan Jesu ni iwọ yio pe orukọ rẹ nitori on ni yio gba awọn enia rẹ la kuro ninu ẹṣẹ won

Gbogbo eyi si ṣẹ ki eyi ti a sọ lati ọdọ Oluwa wa ni ẹnu Woli ki o le ṣe pe Kiyesi Wundia yio loyun yio si bi ọmọkunrin kan nwọn yio ma pe orukọ rẹ ni Emmanuel itumo eyiti Iṣe Ọlọrun wa pẹlu wa"

Nigbati Josefu dide ni oru o si ṣe bi Oluwa ti sọ fun o si mu aya rẹ si ọdọ On ko si mọ titi o fi bi akọbi rẹ ọmọkunrin o si pe orukọ rẹ ni Jesu.

Ẹnyin onkawe mi bi itan Jesu Kirist Oluwa ati



Ọgbẹni J. O. Shoyinka

Olugbala ti ri gan an ni eyi gẹgẹbi ẹnyin paapa ti mọ pe o jẹ Onirẹlẹ enia atipe jandukụ enia toripe ọmọ Ọlọrun ni ṣe o tọ, osi yẹki a tẹle ipasẹ rẹ nipa siṣe ara wa nidi ọti amupara ati iwa ipanle hihu nigbati a ba nṣe ajọyọ ọjọ ibi Kristi.

### AISUN ỌDUN KERESIMESI

Opolọpọ awọn ti nwọn npe ara won ni mọ ẹhin Kristi ni maa gbe ekun ja de ninu aisun ọdun pẹlu ogunlogo awon aladura ni ẹnin won Nwon a si bẹrẹsi na awon ti o nlọ jẹjẹ ara won lọ titi

Bi nwọn ti ngna enia ni awọn ti nwọn ndana sun ile ati moto nsun un pẹlu ina 'BISINKO

Ẹnyin ara mi o to asiko gẹẹ lati dawọ ṣekeṣeke bayi duro lasiko ọdun Onigbagbọ, toripe Jesu ti a ntiti ri rẹ yọ a ọ yi, ki ṣe onijagidijagan enia.

Alafia Oluwa ki o ma a a gbogbo wa gbe. Lẹkansii mo ki ẹnyin onkawe Irohin Imọlẹ pe, e ku ipalẹmọ Ọdun O. Aṣẹyi ṣe ọpọlọpọ ọdun o.

## Iwe si Olotu Irohin Imolẹ

### Omo Abẹokuta, Ẹ Fi Eyi S'Ero

Olotu dakun gba mi ni aye diẹ ninu iwe rẹ oloyinmọmọ lati ba awọn ọmọ Ẹgba 'mọ Lisabi sọ ọrọ ti o ndun mi lọkan lori ipo ti ilu Ẹgba wa ni asiko yi eyiti ko dun mọ awa ọmọ Ẹgba to wa ti le a i loko ninu nigbati awọn miran nwa idagbasoke fun ilu won

Bi a ba fi oju inu wo bi gbogbo nkan ti nlọ, ao ri wipe awa ti ao wa ni asiko yi ko fi gbogbo ara mura si ilọsiwaju ilu wa to bi o ti tọ ati bi o ti yẹ

Itan sọ fun wa pe ilẹ Ẹgba ni o kọkọ gba ominira ninu gbogbo ilẹ Naijiria ni aiye atijọ, nigbati awọn enia na ko mọ iriri rẹ ni Ijọba Gẹẹsi ba tun gba pada lọwọ won nigbana

Awọn ti o tẹle wọn le ominira na ko bọsi rara di oni olani ise ti o wa kan gbogbo ọmọ ibile Abẹokuta ni pe ki gbogbo wa ji giri ninu orun wa ki a wa ọna ti ilu wa na ko fi ni di ero ẹhin ninu ilẹ Naijiria paapa ilẹ Yoruba

Itan ko fi igbakan sọ fun wa pe ilu Abẹokuta wa lasan ero ẹhin ri, a fi ki o jẹ apẹrẹ rere fun awọn ilu miran Gbogbo ẹnyin ọmọ Abẹokuta o di ọwọ nyin o

Mo dupẹ aye ti ẹ gba mi Olotu

Emi ni
L. B. Martins

ABẸOKUTA

### Ọlọpa Ẹ Ran Wa Lowo o

Olotu inu mi yio dun bi ẹ ba le le ọrọ mi yi jade ninu iwe nyin to nta bi akara gbigbona lati kesi ọga agba awọn Ọlọpa to wa ni agbegbe Ikeja lati se iranlọwọ awa enia to ngbe ni ilu Agege nipa ti awọn ọlọsa ti wọn ko pa ti awọn ọlọsa ti wọn ko fun awa enia to ngbe ni ilu na lokanbalẹ atipe ti a ko le sun ile onile.

Mo ro pe o ti lo nkan bi osu melo sẹhin tia ti nkesi awọn Ọlọpa lati le ba awa enia ilu Agege mu oju to iwa ti awọn Ọlọsa na ma nhu fun awa ti o jẹ Onisẹ Ijọba eyiti o jẹ pe ti a ba ti kuro ninu ile wa lọ sibi isẹ to jẹ pe tia ba pada si ile ti a ko ni ba ẹru kankan ninu ile wa mọ.

Inu awa enia ilu Agege ati paa pa julọ awa ti a jẹ osisẹ yio dun bi awọn Ọlọpa ba le tete ba wa mu oju to iwa ti awọn ọlọsa na nhu si fun wa

Olotu mo dupẹ pupọ fun aye ti ẹ gba mi ọkọ gba ko ni sa nyin lese o.

Emi ni
Julius Ademọla

AGEGE

### Ẹgbẹ Dẹmo Ti Ku Ni Ijẹbu Imushin

Olotu, J wo gba mi ni aye rampe si u iwe nyin to kun fun ogbon ati oye lati fi pe awọn jẹusujẹun Oselu to wa si ilu Ijẹbu Imushin, Ijẹbu Ifẹ ati Oru ati Ikija ni ẹkun Ijẹbu pe ko si ẹniti nse egbe Dẹmo ati egbe na si ti ku patapata ni awọn ilu ti mo daruko rẹ yi



O'loye S. L. Akintọla

Eleyi je ohunti o ya mi lenu lati ma ri gbo wipe awọn Ijoye kan ati awọn Ọba ti nwọn ntẹnu bọ lẹ kiri pe awọn lo fẹ ma ko egbẹ Dẹmọ eyti awọn enia ilu ti mo darukọ yi ti kẹnọn si a ti sin oku ẹgbẹ na lojọ to ti pẹ.

Emi si gba pe ẹgbẹ Dẹmọ ti ku ninu awọn agbegbe ti mo darukọ rẹ ati pe ko si eniti o nṣe ẹgbẹ na bikose awọn Ọdalẹ paraрọ ilu Ijẹbu Imushin ni ati awọn ilu yoku lo parapọ nṣe ẹgbẹ na.

Mo si tun kan saara si awọn Obinrin Imushin, Ijẹbu Ifẹ, Oru ati Ikija pe awọn si kẹhin si ẹgbẹ ọdalẹ.

Emi ni
Başiru Lawal
IJẸBU—IMUSHIN

## IWE KOṢEMANI NI EYI
IWE ITỌSẸ OHUN GBOGBO
NINU ODU MẸRINDINLOGUN

Iwe yi kun fun Asọtẹlẹ ati wipe, yio din ọ lowo YEMIWO" ku, nitoripe iwọ na ylo le ma da se AYẸWO fun ara rẹ

"KOSEMANI" ni iwe na, 2/6d pere ni a nta

ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8, Id magbo Avenue
Lagos, Nigeria (Leti Ọja Jankara)

# Kere o Kere o! Akiyesi Pataki




Awa na le ieri wipe Ojulowo hanunhanuu Egbogi na LEOPILLS awa na nlo ni Gold Coast (Ankara Ghana pelu meji re ko si ninu gbogbo orisirisi Egbogi ti o wa ni Ile Naijiria

A wa na jẹwọ ni igboro Ilu Eko, Irohin si o wa lẹnu gbogbo enia tọmọde t'agba ni asiko yi ti nwọn fi se ọrọ ati orin larin ara won nipa Egbogi Jamani olokiki yi ti nwọn npe ni LEOPILLS

Imoran awọn Dokita Oyinbo ti nwọn nṣe iwadi Egbogi LEOPILLS, yi kan ọ wipe bi o ti lagbara to ati bo jẹ Ojulowo giriki ati atamatase fun "JẸDIJẸDI" bi o tiwu ki ọjọ rẹ pẹ to bẹ na ni nwọn si tun fi ọwọ soya tabi pe ile i fun gbogbo awọn ti ami di tabi iju, Igbẹ sise, aiko ri igbọnsẹ deede, inu irun nigbakugba ara wiwo, Ẹsanri ẹhin didun sisan ati aiko riran kedere ko doro buruku ara, aisan Onigbameji ati orisirisi arun miran gbogbo pẹlu

"Wipe nwọn yio ri alafia ni kiakia ti nwọn nba egbogi LEOPILLS nitoripe o tun ma tun ẹjẹ se enia nipa sisọ di ọtun.

RANTI PE ALAFIA LOGUN ỌRỌ IJAFARA SI LEWU PẸLU.

IYE OWO EGBOGI LEOPILLS:— Igo nla sile meje alọ (7/-6 pere Igo kekere sile mẹrin abo (4/6) pere. Bere Ojulowo Egbogi miran fun orisirisi Anta ti e ba fẹ ni Ṣọbu awọn:—

Waterloo Medecine Stores
8 Palm Church Streer Lagos P. O Box 333

ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba
ATI NI ṢỌBU
IṢE OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA
IBADAN

### Angeina Super -- Rose

(O TI LỌ WA JU)

Eleyi sẹsẹ jade ni ko si nita rara Asẹsẹ jade akan ako mọ ibiti o nlọ Ohun pataki ti a mọ nipe "O ti lọ wa ju"

Super rose yi wa fun ipara gbogbo enia lọmọde lagba lọkunrin ati lobinrin O tun wa fun irun didi ati kiko lowo o ema irun ọkunrin pap ma dan ki o si jọlọ O ma fun ara ni ẹwa ak tun awọ ara ylo si yọ jade perepere.

Bi enia dudu ba loo yio mu dan gẹgẹbi jigi Enia pupa kuku ti wa tẹlẹ.

Tere sare watabi ki o kọwe fun tirẹ loni ki o to tan ni West African Cosmetic Industries" 35' Ọmọwunmi St. lẹhin District Council Mushin ẹrọju ara ati irun nyin ẹtọ Owo pọku ni 1/3d fun ẹyọ kan 15/- fun mejila

# IJO APOSTELI TI KRISTI ȘE AJỌDUN KẸTALA

IDI ORO: — Irohin ko to amojuba ni ajọdun alatinṣa ti Ijọ Apo steli ti o wa ni Nomb 6 Iyasuna Street Idi Oro șe ni deede agogo meji ọsan ọbara ti ilẹ ọjọ na mọ ni awọn enia ti nde lati Itirẹ, Shomolu Oshodi, Agege, Ebute Metta, Apapa, Yaba Eko laiko sọ ti awọn enia ti o wa ninu ilu Mushin

Bi ilẹ ọjọ na ti mọ ni awọn obinrin Ijọ ti nṣe ti nwọn nsọ ti awọn orișiriși onjẹ bi amala iyan ẹba fufu iresi moyimoyi ẹlẹmi me je laisọ awọn ọbẹ bi ẹja tutu ẹja yiyan eran malu eworẹ ati agbo

Ni deede agogo mejila ọsan ni awọn enia ti nde ni meji meji, mẹ ta mẹta bi awọn Ijọ Ayika ti de pẹlu ilu ni ijo ba bẹrẹ ti nwọn si njo bi ukoto ni ọjọ na

Alufa J A Agbona ti o je oniwasu ijọ na wọ aṣọ olowo iyebiye bi Ọba ti o nki awọn alejo ku abọ ni ọkọọkan titi isin ajọdun na fi bẹrẹ

Nwọn fi orin bẹrẹ isin na awọn akorin kọ orin bi awọn Angẹli irohin ojo na pọ koja ohun ti enia le sọ tan a fi ọniti o ba de ibẹ ni ọjọ na

Ẹniti o wasu ni ọjọ na ni Alufa Aboge ninu ọrọ ti o fi wasu ni o ti sọ pe o yẹki gbogbo enia dupẹ lọwọ Ọlọrun fun anu Rẹ to da wa si di ọjọ oni o ki Alufa Agbona ku orire fun suru ti o fi ba ijọ bọ lati ọdun mẹtala sẹhin O ni inu on dun pupọ fun ẹmi Ọlọrun ti ko fi alufa Agbona silẹ eyiti o nlọ lati maa fi gbin ọrọ Ọlọrun si ọkan awọn enia

O wa tun dupẹ lọwọ awọn ijọ ti nwọn fi itara nwọn da owo ti o pọ to ẹdẹgbẹta (£4,500) ponun la ti fi ko ile Ọlọrun nwọn, o ni Ọlọrun yio bu si apo ti owo na ti jade wa

Alufa Aboge wa tun gba Alufa to ku ni iyanju ki nwọn mura si a ura ki alafia ati ibalẹ ọkan le tun pada si Ipinle Iwo Orun Naijiria o ni nwọn gbodo tun maa gba awẹ fun alafia ilẹ Yoruba

Ni ipari ọrọ rẹ ni o ti sọ fun gbogbo enia pe ki awon gbiyanju lati sin Ọlọrun Olodumare pelu okan kan ki nwon si ko iwa alufa Agbona ti o fi awon ebi orẹ iya ati baba re sile nitori ọrọ Ọlọrun

Lẹhin ipari isin ajọdun na ni awọn enia ba nfi orin ati ijo dagbere fun ara wọn pe o digba o

Awọn eni ti o wa ni ọjọ na ajẹti ni nwon fi onjẹ ṣe ti nwọn tun ba gbogbo ile O wa ni dudbo na ni onjẹ a fi ẹ iti ko ba koja ni ọjọ na ni ko jẹun ni ajẹti

Diẹ ti awe wa fun ninu awọn eni ti o wa sibi isiri ajọdun na ni Ẹni Ọwọ Z A Aboge, Ẹni Ọwọ R A Adedipẹ, Alufa A Adenrele Alufa A Adedipẹ, Alufa Adedinran, awon alagba ni T Kuku Z A Adeyẹmi, Z O C Oki A Adebakin Bodunrin, Olukoya, A Ikuwa rde Omosanya ati Bassey.

Oju yio ma rodun o ẹ ku inawo

## YE IRAWO RE WO

AQUARIUS (Jan 22 Feb 20) Are yio mu o lon yio si da o lam nitoripe iwoko 'e ba awon isoro waju kujo Kuku gba fun Ọlorun laipe iwo yio si ri alafia

PISCES (Feb 21 Mar 20) Ọjọ oni dara lati fi iwa Irẹpọ pẹlu awọn enia, ki ẹ si da ọjọ ti ẹo jijo ba ara nyin rin Irin ajo, ṣugbọn ki e maṣe jẹki adehun nyin yẹ.

ARIES (Mar 21 April 20) Maṣe lo orisi egbogi pupọ nigbakan ki o ma ba di o lọwọ lati ṣe iṣe rẹ gẹgẹbi o ti se eto rẹ silẹ ma egbe wa re ga ju bi o ti ye lọ

GEMINI (May 21 July 21) Aisan ati aigbadun yio ba ọ jalẹ ni o yẹ ki o rin mọ alagba kan ti yio da o lara Iya damu ọkan yio de si o ti iwo ko ni mọ bi aiye rẹ ti nlo si Kuku jẹ fuji o si ode da aya boya yio san.

TAURUS (April 21 May 20) Ifokanbale ati idẹra yo wa fun ọ jaburata loni Igbadun ati Idẹraya yio wa fun iwọ pelu enikeji rẹ iwo o si gbo irohin al dun iwo yio si ri owo lo

CANCER (June 22-July 22) Ire ati adun po fun o loni ṣugbon o ye ki o kepa ir wẹsi nipa idubule ki o si sun.

LEO (July 21 Aug 22) Ọjo iyanu li oni ti ko ni jeki inu dun sora ki o ma se șe lara ẹnikankan nitori pe ojojo yio ba o

VIRGO (Aug 23 Sept 23) Ode tabi idalẹ ti o ba lo loni yio fa ire wa ba o iwo yio ba o isiri awon enia pa de tobẹ ti ẹnu yio ya o iṣe re yio ma ni ilosiwaju ki o si kowe si awon orẹ rẹ

LIBRA Sep 24 Oct 23:- Arẹ ara le de si ọ loni, ṣugbon ki mo wipe odo rẹ ni gbogbo aiye nfi oju si, ki o si to ju alafia ara rẹ. so ohun ti iwọ yio jẹ loni ki o si lo dubulẹ

SCORPIO Oct 24 Nov 22 Orișirși erongba lo mbẹ lokan rẹ lo si ipade awon enia pataki ki ọ si ba won jiro ro ohun ti o si ngbero ninu okan rẹ ire ni yio jasi

SAGITTARIUS (Nov 23 Dẹc 21) Iwọ yio ṣe ore re nitoripe ninu awon egbe to dara ni iwo wa oro ohun ti o nso nipe owo yio sanfani

CAPRICORN (Dec 22 Jan 21) Ọjọ Ire ni oni yi jẹ fun ọ, ati ire ni ohun ti o nro ninu okan rẹ yio jasi, ṣugbọn ki o ṣọra ki o maṣe ba ẹni kan jo vu, ki o ma ba di ija ati asọ.

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ATI OGO NIPA DYNAMIREN TỌNIKI

ALE-BI-ALE Egbogi Tọniki jamonu, tilu ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ di jufun Agbara ati Ajẹbidan iṣẹ lara agbalagba Ọkunrin ati Obinringbogbo

Bi arẹ ara ba nmu ọ, ni gbakugba fun wahala tabi iṣẹ șișe ti o ko le jẹun dara dara, tabi ki o male sun da da de ọkan lọsan tabi awọn ṣaa ara rẹ gbogbo ki ẹefun daradara ti Emi Breath inu ko ba kuulẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala sise tabi inu awọn ailera gbogbo nyin ti ọjọ ori (age) ba ti kọja ọgbọn ọdun si adọri tabi ubẹ lọ mọ daju pe DYNAMIREN ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara di ọtun pafapata inu rẹ a jẹlọ ẹran ara rẹ ti o ghunjọ yio bi yabo dada ti Ara rẹ yio gbe karkan ni ugba yio sao pẹlu ioq m adun brode o iyẹn d bạș



WATERLOO MEDICINE STORES
8 Palm Church Street Phone 22787
LAGOS Nigeria, (Ọja Ita Faji

LAGOS ISLAND CHEMIST
Victoria Street, Lagos

UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street, Lagos

NIGERIAN MEDICINE STORE
4, Tinubu Square Lagos

# Nwọn De Ọlọpa Meji Mọgi !

ILESE — ILARO:— A gbọ sọ gba nu ni irohin kan ti o de ile iṣẹ wa ni ọjọ Aje ti iṣ o o kẹtala oṣu yi pe awọn kan ti enia ko mọ tun so Ọlọpa meji mọgi ti nwọn tun da ia sun Teṣan awọn Ọlọpa.

Irohin ti a ri gbọ na lati i u Ileshe lẹba ilu Ilaro tun fi yẹ wa pe, awọn ọlopa ti o nṣọ ile iṣẹ awọn Ọlopa Ibilẹ ilu leshe ni nwọn lọ so wọn mọ oke tente o r i igi kan ninu igbo ki nwon to wa lo da a sun ile i ṣ ẹ awon Ọlopa ti nwo n s o

Irohin na ṣe afikun pe nigbati awon ti yio gba iṣẹ de ni nwọn ba ri pe ile iṣẹ awon ti jona di eeru bamu bamu ni nwon ba wa awon Ọlọpa meji kiri nigbati nwọn kori won ni nwọn ba pada lọ jiṣẹ fun ọga Ọlọpa ti o wa ni Ilaro pe nwọn ti dana sun ile iṣẹ atipo awon ko ti foi i kan awọn meji ti o nṣọ ile iṣẹ na

Ọga Ọlopa ti o wa ni Ilaro ba ko awon Ọlopa to to ogun wa si Ileshe ti nwọn bẹrẹsi fọgbo kakiri ki nwọn to ri nwọn lori oke igi kan ti nwọn de wọn mọ danindanin

# YẸYẸNATU

## Lati Oju Ewe Keji

Yẹyẹnatu Ọro melo ni ngo so i ngo fi paro Subẹru ni bi nko ba le so oyinbo a ko ni jo lo si ode odun ti nbo yi

Olotu Ewo lo kan Suberu ninu odun enigbagbọ

Yẹyẹnatu Ẹ fẹrẹ le bere pe ewo lo kan emi Yẹyẹnatu ninu odun enigbagbo

Olotu Yẹs ewo lo kan o

Yẹyẹnatu O dara ewo lo nkan ẹnyin ninu ọdun Imale tabi ẹ ko gba ẹran ti a fun yin ṣe bi nwon ba fun ẹ yin ni nkan ninu ọdun Imale bi odun tiyin ba de ko to ki ẹnyin fun wa

Olotu Ki lo ṣe ipa ni iyẹn

Yẹyẹnatu: A ti mọ ẹnyin kiriyo tẹlẹ Ṣe okun ni ẹ maa lọ lọjọ ọdun ki a mi le ba yin ni ile ?

Olotu: Emi ko tilẹ ni lọ si okun. Mo si ti ra ẹlẹdẹ ti mo fẹ fi ṣe ọdun Ngo maa reti iwọ ati Suberu o

Yẹyẹnatu: Hahaha ! ẹ ṣe mistake Ẹ lọ ra ẹlẹdẹ ki awọn imale ma le wa ki nyin Hahaha bi iyẹn awọn oni gba gbọ ododo Emi ko si ni ara won I g b a t i ọdun igbagbọ wo yi de nko le fi ẹjọ ṣire, ẹ ma a reti mi

Olotu: Bi Suberu ko ba wa nko gbọdọ ri ọ

Yẹyẹnatu: Ha ! Bi nba ti wi fun pe ẹ ma a pa ẹlẹdẹ, dajudaju yio wa

Olotu: Mo nlọ si Ibadan lọjọ ọdun ṣa

Yẹyẹnatu; Hawu, ẹni nla ni ẹ ṣe fun wa, a gbọdọ tẹle yin lọ. T a b i ẹ n y i n ni ẹ fẹ di Gomina.

Olotu: Gomina bawo ?

Yẹyẹnatu: H wa igbati ẹ s ni ẹ fẹ fi Eko silẹ lọ si Ibadan ni ọjọ ọdun, o ya mi lẹnu ni

Olotu: K ni iyanu to wa nibẹ ?

Yẹyenatu: Bawo ni enia ṣe le fi Eko sile lọjọ ọdun lọ si W e s t ti nwọn nku yen ayafi bi Oluwaro ba fe di Gomina lo ku, nitori ipo nla ni

Olotu: Wo o, yago fun mi lọna, o jare

Yeyenatu Hawu e ma ti mi suba e jowo si i, o dabọ o.

# Ila Kini eleyi O




OGUN A PA YANMU — YANMU
LORI ERIN MẸTA NI

Three Elephant Brand mosquito coils d ra pupọ An O dara ju gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ

O npa yanmuyanmu ninu ile ni kiakia orun rẹ si da ra pupo ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ Bakanna ni o si tu ara pa ayan ati idun

Tete lo ra packet ogun yanmuyanmu Three Elephant Brand coils tirẹ loni, ki o si dan wo, iwọ yio ri bi o ti ṣe pa gbogbo yanmuyanmu inu ile rẹ ti iwọ ati awọ ọmọ rẹ yio si sun daradara

Kiyo ri daju pe ogun yanmuyanmu o ori erin mẹta yi ni nwọn mu un ọ

Three Elephant mosquito Brand coils yi wa ni ṣọbu Alaitaja kakiri Orilẹ ede yi

DISTRIBUTORS
AMOS GBENLE & BROTHERS
34, Decemo Street, Lagos
6 & 11 Balogun Street, West
LAGOS

BERE FUN OJULOWO ADI ELEGBO
"Congreve's Iodo Form--Ointment'



Atamatase ni egbogi " ADI-ELEGBO" yi i fun itọju gbo gbo oriṣiriṣi "EGBO—ẸSẸ" ni kiakia bi o ti wun ki jọ rẹ ti le pẹ to, Adie'egbo yi ko ni ẹgbẹ nipa wipe awọn ko idọti ni bi ẹrọ gbogbo ti ba wa loju egbo patapata lade oju re yio s mo daradara .Lẹhinna oju egbo ti o ba jin si u yio je i oju re ru wa soke, yio si pọn daradara run itakuru ko si mo aeiewere ni yio si san patapata. Alafia de si ọ niyen : -

Ri daju gbangba wipe awon sobu ti a da oruko won si isale iwe yi ni egbe ranṣe lọ ra Bibeko awon Eleru tabi onijibiti yio ta 'Adamodi' re fun o maṣe gba ra o.

Bere egbog yi ni ṣobu awon :—

Waterloo Medecine Stores
8 Palm Church Streer Lagos P. O Box 333

# IROHIN IMOLE

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE TẸNI GBOGBO LAWA

NO 1,589 SATURDAY DECEMBER 18, 1965 (2D)


## Ọgbẹni Njoku T'ajo De

EKO:- Ni ọjọ ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu yi ni Minista Alamojuto eto waya fun apapo Ijọba Naijiria Ọgbẹni Raymond Njoku pada de lati irinajo ti o ṣe si ile New Zealand nibiti o lọ ba wọn ṣe eto ipade kan eyiti iṣe ti Ajọ gbogbo gboo ti orile ede agbaiye ti iṣe ti awọn Igbimọ Asofin.

Ọgbẹni Raymond Njoku ko le pada de si ilẹ Naijiria ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹrinla oṣu yi gẹgẹbi irohin ti o kọkọ de ile iṣẹ wa pe ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹrinla oṣu yi ni Minista na yio ba ọkọ ofurufu de si ilẹ Naijiria ati pe ohunti o fa eleyi wa ni oju sanma ti ko dara fun ọkọ ofurufu lati fo lọ da eleyi sile ti Minista na ko fi le de

Ọgbẹni Njoku ba awọn oniwe irohin ṣe eto ipade kan ninu ile iṣẹ rẹ lori irinajo ti o ṣe si ile Asia ati nipa ti eto ipade ti Ajọ gbogbo gboo eyiti awọn Igbimọ ẹgbẹ na ṣe lori eto iṣelu ni ilẹ Washington.

ẸGBẸ ODO AFENIFERE MUSHIN SO PE :

# AWỌN KO NI IGBẸKẸLE NINU IJỌBA EGBẸ DẸMỌ

MUSHIN:- Ninu ipade kekere kan ti awọn ọmọ ẹgbẹ ọdọ Afẹnifẹre ilu Mushin ṣe ni ibẹrẹ ọsẹ yi ni nwọn ti sọ wipe, awọn ko ni igbẹkẹle ninu Ijọba Aparutu ti ẹgbẹ Dẹmọ ni awọn nṣe ni Ipinlẹ Iwọ Orun, nwọn tun ni ibo ti nwọn di ni ọjọ kọkanla oṣu kẹwa ọdun yi ni Ipinlẹ Iwọ Orun jẹ ibo ti enia ko gbọdọ ka kun ibo rara ati pe ọna iwa ijamba ati ti imọtara ẹni nikan ni awọn ẹgbẹ Dẹmọ fi di ibo na, nwọn ni aditi ati afọju mọ wipe eru wa ninu ibo na.

Ọrọ ti akọwe ẹgbẹ ọdọ Afẹnifẹre Ọgbẹni S, A. Okemakinde so fun oniwe Irohin wa ni o ti sọ wipe, awọn koni igbẹkẹle ninu Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun eyiti ẹgbẹ Dẹmọ nṣe akoso rẹ bayi ati pe awọn ofin ti nwọn ṣe ninu ile Igbimọ Asofin Ipinlẹ Iwọ Orun ni ọjọ kẹsan oṣu yi ko ya awọn lori.

Akọwe ẹgbẹ ọdọ Afẹnifẹre ti Mushin tun sọ pe awọn ti kesi Gomina Ipinlẹ na Ọlọla Ọdẹlẹye Fadahunsi pe, ki o ma ṣe fi owọ si ofin ti nwọn ṣe rara, nwọn ni ipade na ko ba ofin mu rara nitoripe ko si ipade Igbimọ Asofin ti yio ṣe ti Gomina ki iwa nibẹ ati pe ki o tun so ohun meremere ti Ijọba rẹ yio ba ṣe si ilu,

Nwọn ni ibo ti nwọn di koja yi ni Ipinlẹ Iwọ Orun ko dara to rara, ati wipe alaga Igbimọ ibo Ọgbẹni E. E. Esua, ti so wipe ona ẹru ati magomago ni awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ gba fi wọle ninu ibo ti nwọn di na eyi ti ko ba ofin ilẹ Naijiria mu rara,

Nwọn ni awọn ẹgbẹ Dẹ-mọ ko fun awọn enia ti o nṣe iṣẹ ni aye lati dibo paapa nwọn ko tun fun awọn enia Ipinlẹ Iwọ Orun lati yan eniti o wu won lati ma a ṣe Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun.

Ẹgbẹ Odo Afenifere tun so siwaju si rẹ, Oloye Samuel Ladoke Akintola ko le ṣe Ijọba le awọn enia Iwọ Orun Naijiria lori bi nwọn ko ba ni ife si ijọba rẹ nwọn ni awọn ohun ti o nṣẹlẹ yi fi nhan pe, nwọn ko nifẹ si Ijọba ti Oloye Akintola nṣe akoso rẹ.

### SOJA

Ẹgbẹ odọ Afẹnifẹre wa kesi Ọlọla Alhaji Abubakar Tafawa Balewa Ala koso Apapo lori oro ti o so nigbati o ti ilu Ghana de pe, kiko awọn olopa ati Ṣọja losi Ipinlẹ Iwo Orun Naijiria ko le ran ohun ti o wa ni Ipinlẹ na, awọn enia to wa nibẹ ni awọn le ṣe atunṣe to wa nibẹ

Nwọn tun kesi Oloye Ọdọfin Bello Olori Ọlọpa Ibilẹ pe ki o tete so ti ẹnu re lori awọn apoti ibo ti Olori eto ibo Ọgbẹni Esua ni on ko fi pamọ ti nwọn ko gbodo fun ẹni kan titi ti yio fi di owuro ojo ti nwon yio dibo eyi ti awọn ẹgbẹ Dẹmo ti pin fun ara won ki o to di ojo ti won dibo

Nwon wa tun kilo fun Alhaji Balewa pe ko gbodo pe Oloye Akintola si ipade awon alakoso ti o wa ni ilẹ Naijiria nitori pe ibo ti won di koja ni ọjọ kokanla osu kẹwa odun yi ko ja gere ẹgbe na nsoro lori ipade awon alakoso Ipinlẹ to wa ni Naijiria ti nwon fe so ni ose to koja

Irohin na tun so pe Oloye Akintola ko fi ọna eto wole sinu ile Igbimo Ijoba Ipinlẹ Iwo Orun eyiti nwon se ni aipe yi nwon ni nitori idi eyi Oloye Akintola ko fi ona eto ti ona ofin ile Naijiria je alakoso

Ni ipari oro won ni won wa kesi awọn alakoso Ijọba Ila Orun Naijiria Dokita M I Okpara pẹlu alakoso ijọba Agbede meji Iwọ Orun Naijiria Oloye Dennis Osadebey pe nwon ko gbodọ lọ si ipade ti Oloye S L Akitola ba wa nibe Nwon ni ti nwon ba le fi lọ pẹ a jẹ wipe nwon fi iya jẹ ọkẹaimoye Ọmọ ẹgbẹ (UPGA) to wa ni Ipinlẹ mejeji

Nwon wa pari ọrọ nwon pe awọn enia Ipinlẹ Iwo Orun ko gbodo ka Oloye Akintola si alakoso Ipinlẹ na.

## Lati Oju Ewe Kini

ẹgbẹ Afẹnifere Alhaji D S Adegbenro ati Oloye iya abn Hannah Awolowo jiroro lati le pari ija na eyiti yio mu ki rogbodiyan to ṣẹlẹ ni Ipinlẹ na lelo si opin.

Nigbati oniwe irohin wa to wa ni ilu Ibadan fi oro wa Alhaji D. S Adegbenro lẹnu wo lori ẹro gbohungbohun nigbati awon Igbimọ ẹgbẹ awọn Obinrin na ba Alhaji Adegbenro soro tan ti mo bi nwon ti ṣe pari oro na ni oniwe iroh wa tun ṣe alaye pe Alhaji D, S Adegbenro ku a lati jẹ ki on mọ ohun ti awọn jiroro le lori nipa ọrọ ti awọn Igbimọ na ba sọ

Ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹtadinlogun oṣu yi ni Alhaji Adegbenro de si ilu Eko lati ba awọn Igbimọ ẹgbẹ rẹ jiroro lori ọrọ ti awọn Igbimọ na ba sọ lati le ri pe awọn pari ija to wa larin ẹgbẹ UPGA ati Dẹmọ

Oniwe irohin wa fi ye wa pe lori ọrọ ti Alhaji D S Adegbenro fi dahun lohun ninu ẹrọ gbohungbohun ti fi han pe ko gba lati le jẹ ki awọn pari ija na afi ti nwọn ba tu Ile Igbimọ Asofin Ipinlẹ na ka lati ṣe eto ibo miran lori ona eto ofin laisi magomago gẹgẹbi eyiti o ja lọ kọ yi.


Printed & Published Mopupe Printing Press 16, Bamgbosẹ Street, Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street, Lagos 18/12/65